William Bascom, Director
Museum of Anthropology
University of California
Berkeley 4, California

# TAN' T' OLORUN

NIPA

A. K. AJISAFE

PRINTED BY
THE IFE-OLU PRINTING WORKS
21, Kakawa Street—P. O. Box 756.
LAGOS. NIGERIA.

14

## AKIYESI

Işipaya awọn iwe ti o yẹ ki a ni lọwọ, ki a si ka l'akaye fun igbesi ati ilo wa laiye. Awọn iwe yi kọ ni l'Ẹkọ akọpe nipa ọna ti a fi le ni alafia ati itẹlọrun laiye. Bi enia ba ka wọn laka tan ti o ba si tẹle Ẹkọ inu wọn, ko si ifoiya fun laiye, ọkan rẹ yio si balẹ nitori ti o mọ ọna ti on yio fi huwa lati tẹ Ọlọrun ati enia lọrun. A nta awọn iweyi ni sisi-sisi.

### IWE TANT' ỌLỌRUN. 2/14

Iwe yi kọni bi itobi ati ọla nla Ọlọrun tiri ati pe bi a ba fi otitọ gbẹkẹ wa le E, a ki yio damu, a ki yio şegbe bẹni a ki yio pasan laiye. **6d.**

### IWE ENIA ŞORO 22-23

Iwe yi kọni pe ki a maşe gbarale enia ninu ọna wọn gbogbo ati bi ibayọyọ, iyẹnisi enia ati ileri rẹ ti jẹ omulẹmofo to **6d.**

### IWE IGBADUN AIYE. 24

Orukọ iwe yi ti fi itumọ rẹ han ni, eyi yi ni pe ẹkọ inu rẹ kọ ni pe bi a ba fẹ gbadun aiye ki a si jẹ igbaduu yi pẹ, o yẹ ki a ka iwe yi ki a si fiyesi ẹkọ inu rẹ lórò̀ri **6d.**

### IWE AIYE AKAMARA. 21

Iwe yi kọ ni li ẹkọ pupọ nipa aiye, işoro rẹ, ati oniruru ẹkọ to yẹ ki enia mọ lati tọ işisẹ rẹ, ilosi ati ihuwa si ẹnikeji rẹ ni aiye aladun yi; o kọ ni li ọna ti a fi le tete mọ ibiti kòtò ati gégélé wa laiye ki a ma şubu larin igbadun aiye wa. **6d.**

### IWE ORIN (ẸLẸKỌ AKỌPE) LI OHUN ILẸWA FUN AWỌN ỌMỌ-ILEWE. 6//

A pin iwe yi si apa meji ki owo rẹ ma ba pọju fun awọn obi lati ra fun awọn ọmọ wọn.

Awọn ọrọ inu iwe yi jẹ işipaya ọrọ ijinlẹ ẹkọ fun awọn ọmọde lati tọ wọn si ọna rere ni ihu... ati igbesi aiye wọn. A fi ohun orin aladun ilẹwa k...on ki awọn ọmọde ma ba le gbagbe ọrọ wọn lati le ma ranti nigbati akanşe ohun ti ẹkọ kọkan ba kọ ni ba şẹlẹ. **6d.**

# AKIYESI.

ẸNITI o ṣe iwe yi ko ṣe e nitoripe iwa rẹ dara a ko ri iru rẹ ri; A tilẹ le sọ pe iwa rẹ buru, a ko ri iru rẹ ri.

Nigba pupọ li awa a ma sọ wipe awọn oniwasu gbigbona tabi awọn oniwe to kun fun ẹkọ rere ko nhuwa rere gẹgẹ bi iwasu tabi ẹkọ rere wọn. Ọran itiju li eyi jasi ṣugbọn o fi dara ni. Eyi fihan pe Ọlọrun nikan lo pe ati pe laisi Ọre-ọfe Rẹ ko si ohun ti ẹnikan jamọ. Oyẹ ki eyi tubọ fun ni lagbara ati itara lati ma ṣi ara ẹni leti; o si yẹ ki ẹniti a nṣi leti ki o tubọ ma ronu ki o sima ṣọra nigbagbogbo pẹlu adura.

O ko gbọ bi Paulu Apọstili ti wi? O ni. "Ẹ ba mi gbadura pe lẹhin gbogbo iwasu mi. ki emi na ki o maṣe di ẹni itanu kuro lọdọ Ọlọrun."

Akoko yi jasi akoko ti a le wipe "emi aiye ru. Ọbẹ aiye kan" nitoripe ko si ibiti nwọn ko ako adiẹ alẹ nisisyi nipa ode lile. Nitorina ni mo ṣe gbidanwo lati kọ iwe yi lati fi itunu fun ẹniti ọkan rẹ mbajẹ; ireti fun olupọnju; iṣiti ati ikilọ fun alainironu ati adagbamadanu: nitoripe titi o fi di oni oloni ọpọlọpọ koi ti mo pe Ọlọrun mba araiye wi, Ọpọlọpọ lo si mbẹ ti o jẹpe kaka ki ohun ti wọn nri mu wọn sunmọ Ọlọrun, nwọn tubọ njina si I ni.

Bi iwe kekere yi ba mu ọ fẹ Ọlọrun li *Afẹtan* ti o simu ọ gbe Orukọ Rẹ ga nipokipo ti o wu ki o wa, njẹ wahala ati ajo mi ko bọ si asan ṣugbọn Iyin ati Ogo na jẹ ti Ọlọrun.

Njẹ iwọ ti yio ka iwe yi adura mi fun ọ ni pe ki Ọlọrun ki o maṣai jẹ ki o mọ On ju ohun gbogbo lọ Ki On ki o si ṣe atubọtan rẹ ni rere fun ọ nipati ẹmi ati nipati ara. Amin.

Emi ni olufẹ rẹ totọ,

A. K. AJIṢAFẸ.

*Nigeria,*
*November 13, 1919.*

# IFIJUBA.

Fun Ogo Ọlọrun ati fun imọ agbara ati titobi Rẹ.

Kiyesi i, Ọlọrun tobi, awa kosi mọ bi O ti tobi to!—*Jobu 36, 26.*

A. K. AJIṢAFẸ.

*January, 1921.*